

# **COVID-19** Child Care Stabilization Grant Funding Opportunity Round Two

January 3-23, 2022

MARYLAND STATE DEPARTMENT OF EDUCATION
EQUITY AND EXCELLENCE

## EKA ETO EKO TI IPINLE MARYLAND

**Mohammed Choudhury**
Akowe-Alakoso Owo fun Alabojuto Awon ile-iwe ti Akowe-Owo-owo, Igbimọ Ẹkọ ni Ipinle Maryland

**Deann M. Collins, Ed.D.**
Igbakeji Alabojuto, Eko kiko

**Steven Hicks**
Oluranlowo Alabojuto , Eka Awon Omode

**Larry Hogan**
Gomina

## IGBIMO ETO EKO TI IPINLE MARYLAND

**Clarence C. Crawford**
Aare, Igbimo Eto Eko ti Ipinle Maryland

Charles R. Dashiell, Jr., Esq. (Igbakeji Aare)

Shawn D. Bartley, Esq.

Gail Bates

Chuen-Chin Bianca Chang

Susan J. Getty, Ed.D.

Vermelle Greene, Ph.D.

Jean C. Halle

Dr. Joan Mele-McCarthy

Rachel L. McCusker

Lori Morrow

Brigadier General Warner I. Sumpter (Ret.)

Holly C. Wilcox, Ph.D.

Kevin Bokoum (Omo Egbe)

# Itoka Akoonu

Kí ni igbekale ìnáwó tí ó wà fún itoju àti imumoduro wá fún? ....3
Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà fún imumodúró apá keji?....Error! Bookmark not defined.
Ta ni ó ní eto sì?....4
Èélọ ní a lè san fún eto yìí?....5
Kí ni àwọn àpẹẹrẹ lórí gbígbà owó ètò yìí?....7
Báwo ni moṣelè kopa láti lè gbà owó yìí?....8
Àwọn ìwé àti alaye wo ní mi ní láti ni kìí to lè kopa?....8
Nígbà wó niętọ náà yóò parí?....8
Kí ni yóòṣẹlẹ̀ lẹ́yìn tí ń bá kọ ìwé láti kópa?....9
Igbese wó ḅwà fún sísan owó yìí?....10
Lórí kí ni mo lè na owó yìí sì?....11
Ǹjẹ́ mo ní láti tọju ìwé ẹri fún inawo yìí?....12
Ìbéèrè?....13
Tí mòba nilo iranlowo láti kópa ńkọ́?....13
Awon ibeere ti o saba maa n jeyo lori iranlowo owo....14
Asomo:....15
Awose Itosona láti kọwé fún iranlọwọ owo....16
Foomu Owo Ifipamo Taara....24

2022 v.1.0

# Ki Ní Igbekale Ìnáwó Tí Ó Wà Fún Ìtọ́jú Àti Imomo Dúró Wá Fún?

Ìjọba Biden gbé Okandinlogoji billion dollars kale nínú owó America Rescue Plan (ARP) fún àwọn ìpínlè, ìletò àti ẹ̀yà láti lè ṣe itọju àwọn ọmọ tó ní ìṣòro COVID-19. Owó yìí yóò rán àwọn tó ń ṣe itoju ọmọ àti àwọn olùkọ́ àwọn ọmọ wẹ́wẹ́. Àwọn olùtọ́jú ọmọ wọ̀nyí tí ń kópa láti máa tọju àwọn ọmọ ósise tí ó ṣe pàtàkì, wọn si tún kún àwọn òbí lọ́wọ́ láti máa tètè pàda ṣenu ìṣe wọn. Láti lè mọ síwájú sii nipa igbekale owó yìí, te botini yii.

Ìnáwó yìí jé apa keji tí Igbekale Ìnáwó Fún Ìtọ́jú Àti Imomo Dúró ti Maryland. Ẹ̀ka àwọn omode láàrin Eka Eto Eko ti ipinle Maryland ń pèsè owó yìí láti lè bójútó ìṣòro tí ó dojúkọ àwọn olùtọ́jú àwọn ọmọ èwe wọn yìí àti láti lè bójútó àwọn idiwo tí ó dojúkọ àwọn ń kán rírà láti tọju omo. Awon owó wọ̀nyí je ipese pàtàkì tí yóò lànà ipadabo sípò oro aje àti ọjọ́ iwájú tí ó ṣe pàtàkì.

Ni igba iwowe ọdún 2021, Eka Eto Eko ti ipinle Maryland gbé $158 million kalẹ láti firán àwọn olùtọ́jú àwọn ọmọ wọ̀nyí lọ́wọ́, tí ó ju ẹgbẹrún márùn-ún lo jákèjádò ìpínlè náà èyí tí a lè pè ní apá kinni ìná wó yìí. Àwọn Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yóò tún gbé $128 million èyí tí ó kú fún àwọn olùtọ́jú àwọn ọmọ wọ̀nyí.

# Ki ni Ìyàtò Tí Ó Wà Fún Imomo Dúró Apá Kejì?

Iyato gboogi meta ní ó wàláàrin owona túntún yii àti ti Eka Eto Eko ti ipinle Maryland àkókò:

### IGBESE

Àwọn Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland tí gbó ipa tí àwọn olùtọ́jú èwe àti àwọn alábòójútó àgbègbè lórí àwọn ìbéèrè tí ó jẹyọ àti àwọn ìdojúkọ tí ó wà. Àwọn Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland ní ìrètí láti gba ona tóóró àti láti lọ àwọn oluranlowo mììràn. Àwọn oluranlowo mììràn tí yóò mú ìnáwó náà pọ̀rùn ju ti tẹlẹ̀ láti lè jẹ ki òpó lè nipa, awonolùtọ́jú ipinle naa ti won to Egbaatalegbefa (7200).

### ÌNÁWÓ/ÀTI BÍ A SEPÍNÍN

Ìnáwó apá keji kérésì ti apá kínní nítorí gbogbo owó tí ó wà je ($128million tí a bá wo sì $158million tí apá kinni) pínpín owó náà sì yàtò sì ara wọn, nítorí ọ̀nà tí à pín owó sì yàtọ̀ ($10,000 yàtò sì $15,000). Ní àfikún, owó yìí pèsè ifikun fún owó tí a ti pèsè sílè kọjá ìpín fún àwọn tó ní ìwé àṣẹ itọju fún ọmọ kọ̀ọ̀kan.

Ìpín yìí yàtò láti orí olùtọ́jú tó ní ìwé àṣẹ fún itọju àwọn ọmọ àti ìwé àṣẹ láti tọju ọmọ èwe àti láti gba àwọn ọmọ tó ní ipa ninu ètò eko ọfe fún àwọn ọmọ tí á ń toju, tí ó sì jẹ lara Maryland EXCELS program, èyí tí ó wà nínú àkọsílẹ̀ ìkànìyàn tí ó sì ní mẹ́fà tàbí jù bẹẹ lọ nínú àwọn ọmọ tí ó lè ní àìlera, tí wọ́n pèsè ọwọ láti ìpín $0 si $630 fun ìkookan nínú àwọn tí ó ní ìwé àṣẹ.

### ÌPÍNNINI

Ìpín tí àkókò lórí imuduro àwọn ọmọ tí ó wà fún àwọn olùtọ́jú tí ó ni ìwé àṣẹ sì sílè láti ojo kọkànlá oṣù kẹta ọdún 2021. Èyí tí ó tún sì sílè fún àwọn tí Eka Eto Eko Ipinle Maryland fun ni ìwé àṣẹ lẹhin ojo kọkànlá oṣù kẹta ọdún 2021.

# Ta lo ni eto?

Ìnáwó yìí jé eto tí á gbékalẹ̀ láti lé mú ìpín fún àwọn ilé olùtọ́jú àwọn ọmọ tí ó tì wá nílé, kii se fún láti bẹ̀rẹ̀ Igbekale itoju àwọn ọmọ tí kò tíì bèrè rárá. Àwọn tí yóò kopa lè jẹ́ olùtọ́jú àwọn ọmọ tí ìdílé, àwọn ọmọ ìdílé tí ó tobí, tabi awọn olùtọ́jú ọmọ tàbí ilé ẹ̀kọ́ ọmọ tí ó ní ìwé ase. Láti ni ìpín tàbi ètò ó gbọ́dọ̀ wá ní ìkan nínú àwọn tí à ká sílèyii:

| Oniwe Ase / Ilana Ofin | Ipo |
|---|---|
| Eto itoju mi gba iwe ase lowo Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland ni tabi ki o to Ojo Kokanla, Osu Keta, Odun 2021<br><br>Tabi<br><br>Eto itoju mi gba iwe ase lowo Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland leyin Ojo Kokanla, Osu Keta, Odun 2021 | Ile itoju mi ti wa ni ikale lati toju omo ni ojo iseto yii.<br><br>Tabi<br><br>Ile itoju mi wa ni titi fun igba die nitori aisi owo tabi nitori arun COVID, sugbon yoo w ani sisi lati toju awon omo lati Ojo Keje, Osu Keta, Odun 2022. |

Ni Afikun:

- Àwọn tó kópa tí wọn sì gbà owó ni ìpín àkókò, wọn ní eto láti gbá owó ni ìpín keji
- Àwọn tí ó kópa tíwón ní ju ilé ìtọ́jú kan gbọ́dọ̀ fi ìwé ikopa ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ hàn ní lórí ibì ìtọ́jú naa

# Elo ni owo ti a o san fun eto yii?

Gbogbo àwọn olùtọ́jú tí wọn ní ètò wọn yóò gbà $10000 ni ìbéèrè. Àfikún owó a ó pèsè fún gbogbo àwọn tí ó bá yege nínú ìlànà tí a kà sílè yii:

| | |
|---|---|
| Awon omo owo (Ose meta si Osu Mejila) | afikun $126.00 fun olutoju omo kookan ti o wa labe iwe ase |
| Awon ewe (Osu Metala si Osu Metalelogun) | afikun $126.00 fun olutoju awon ewe kookan ti o wa labe iwe ase |
| Olutoju omo ti o ni eko ofe*** | afikun $126.00 fun olutoju omo kookan ti o wa labe iwe ase ti won kopa ninu eto eko ofe |
| Maryland EXCELS | afikun $126.00 fun olutoju omo kookan ti o wa labe iwe ase ti won n kopa ninu eto Maryland EXCELS ti o si ni ipin Ookan si Marun-un |
| Awujo ti o ni ipalara | afikun $126.00 fun olutoju omo kookan ti o wa labe iwe ase ti eto ikaniyan fiwon sabe awujo ti o ni ipalara ti ipin won koja mefa |

*Àwọn owó tí wọn kó lo nínú ìpín tí a pèsè fún àwọn olùtọ́jú àwọn ọmọ tí kò béèrè fún àwọn owó wọ̀nyí ni à ó pín fún gbogbo àwọn olùtọ́jú àwọn ọmọ ni ọkàn-ó-jokan fún àwọn tí ó ní ìwé àṣẹ

**Àwọn Eka Eto Eko Ipinle Maryland yóò lo ìyè ìwé àṣẹ tí ó wà níikawo wọn ní ilé iṣẹ wọn láti Ojo Keedogun Osu Kejila lati se isiro owo ti won yoo naa seto naa

***Nítorí owó pínpín yìí, Eka Eto Eko Ipinle Maryland yóò ṣe ayẹwo ẹtọ lórí boya ile itoju ti fi iwe iye-owo ise ranse laarin Osu Kefa Odun 2021 si Ojo Keedogun, Osu Kejila odun 2021.

Itọju àwọn ọmọ ẹlẹko ófé tí à mọ si iranlowo itoju omo, pèsè iranlọwọ owó fún itọju àwọn ọmọ fún àwọn ẹbí tí ó ń sise ni Maryland. Fún àfikún àlàyé nipa eto awon omo eleko ofe, tẹ botini yìí here.

Àwọn ètò Maryland EXCEL je àwọn tí wọ́n ń ṣe ẹtọ àti ìlọsíwájú ètò tí ó yege láti oókan sìa arun fún itọju ọmọ àti èkó alakobere tí ó jé òhun tí orileede ń wo fún àpẹẹrẹ rére àti èyí tí ó yege jùlo nínú igbesẹ̀ rẹ̀. Te botini yii here fun ekunrere alaye lori Maryland EXCELS

Gege bíi àkọsílẹ̀ Ile-ise tii ri si isakoso arun "Awujo ti o ni ipalara ni awon nnkan ti o akoba fun awujo nitori wahala ti o deba ilera eda" Àwọn àìlera yìí, The social vulnerability index (STI) nínú àkọsílẹ̀ ìkànìyàn rí wi pé Aárundínlógún ona ni ó ń fà àwọn àìsàn wọnyìí. Àwọn ètò ìkànìyàn ẹ́ àwọn ›› yà ìpínlè èyí tí ó rí pé àwọn ọ̀nà àárìndínlógún yìí, èyí tí à lè pín sí àwọn ohùn tí ó lè fà sababi bíṣẹ̀, àìníanfani si ọkọ, ati ile elero. Ni pato, igbelewon yii lo (wo ate kinni isale yii):

## SOCIAL VULNERABILITY

| | |
|---|---|
| Ipo oro aje | Kere si ipo otosi |
| | Alainiselowo |
| | Owo osu |
| | Ko si iwe ipari ile-ẹkọ giga |
| Akojo ìdílé ati ailera | Arunlelogota odun tabi ju bee lo |
| | Etadinlogun odun tabi o din |
| | Alagbada ti o ni ailera |
| | Awon ile olobi kan soso |
| Ipo eya keekeekee ati ede | Eya keekeekee |
| | Ọdun marun-un tabi ju bee lo ti o n sọ ede Gẹẹsi to 'Kere si daradara' |
| Iru ile gbigbe ati igboke gbodo oko | Opo ile aladani akopo |
| | Awon ile alagbeka |
| | Ogunlogo eeyan |
| | Ko si oko |
| | Ile olopo eeyan |

Orisun (gbaa ni Ojo Ketalelogun, Osu Kejila Odun 2021):
https://www.atsdr.cdc.gov/placeandhealth/svi/documentation/SVI_documentation_2018.html

Awọn olupese tun lẹṣabẹwo si ibi here fun alaye diẹ sii ati awọn iwe nipa Atọka Ohun Ipalara Awujọ

# Ki ni apeere awon iye ebun ifunni?

## ISELE KINNI

A fun awon ti o n pese iboju to omo ni aadota iwe ase lati gba omode ati omo ti o sewiole sugbon eyi ko ba ilana afikun owo wi:

*Ipile Ifunni= $10,000*

*Iye okookan iwe ase= $126 (Ilana ikoko to doju ami) + $126 (Ilana omode to doju ami) = $252*

*Gbogbo apapo afikun Dola= $252 * 50 iwe ase ti a fun ni = $12,600*

*Apapo ifunni= $10,000 + $12,600 = $22,600*

## ISELE KEJI

Olupese itoju fun omode ti o ni iwe ase fun aadota aaye ti ko pegede lati je anfani afikun owo nitori o kuna ninu osuwon yii:

*Ipile ifunni= $10,000*

*Iye okookan iwe ase= $0*

*Gbogbo apapo afikun Dola= $0 * 50 iwe ase ti a fun ni= $0*

*Apapo ifunni= $10,000 + $0 = $10,000*

## ISELE KETA

Awon olupese itoju fun omode ti won ni aadota iwe ase magba awon ikoko ati omo-owo, gba omode ti won kopa ninu eto owo iranlowo fun awon omode ti ikejo:

*Ipile ifunni= $10,000*

*Iye okookan iwe ase= $126 (Ilana ikoko to doju ami) + $126 (Ilana omode to doju ami) +*

*$126 (CCS to doju ami) + $126 (EXCELS to doju ami) +*

*$126 (SVI to doju ami= $630*

*Gbogbo apapo afikun Dola= $630 * 50 iwe ase ti a fun ni= $31,500*

*Apapo ifunni= $10,000 + $31,500 = $41,500*

# Bawo ni mo se maa j'anfani owo yii?

Anfani igbe owo sile yi, pelu gbogbo awon asomo ati awon imudojuiwon, ni a rii lori oju-iwe weebu ti ipin Ibere omode [the Division of Early Childhood website](). **Eka Eto Eko ti ipinle Maryland n gba awon ibewe ori ayelujara nikan nipase ona asopo. Jowo mase fi awon eda iwe, fasi, tabi awon ibewe ti a ko/tite jade ranse.** Awon ibewe ti a fi sile lori ayelujara nipase ona asopo iwadi nikan ni yoo gbero. Eda PDF ti ibewe naa wa ni opin itosona yii ki awon olupese itoju omode le bere lati mura sile fun ifisile won siwaju. Awon olupese ti o ni anfani konputa tun le fi ibewe won sile nipase ona asopo weebu lori ero alagbeka won.

# Awon iwe ase ati alaye wo ni mo nilo lati pari ibewe naa?

Saaju ki o to bere ohun elo ori ayelujara, awon olupese ye ki won ko awon iwe wonyi jo:

- Nomba idanimo Olupese re (nomba mefa ti o wa lori ijabo ayewo re)
- Eda oni-nomba ti iwe-ase re tabi ijerisi iforukosile; tabi leta ifarada.
- Iwe-ase re tabi nomba iforukosile (ti a rii lori iwe-ase re tabi ijerisi iforukosile)
- Imudojuiwon Foomu W-9 (se igbasile eda kan nibi [here]())
- Foomu idogoadawin, ti o ba fe lati gba owo-sisan re nipase Ohun idogoadawin(se igbasile eda kan nibi [here)]()

# Ki ni akoko fun owo eto yii?

Anfani igbeowosile, pelu gbogbo awon asomo ati awon imudojuiwon, ni a rii lori oju-iwe weebu ti ipin ibere omode [the Division of Early Childhood website](). Lati beere fun isanwo eto yii, awon olupese gbodo pari ibewe ori ayelujara nibi [here]().  . Eda PDF ti ibewe naa wa ni opin itosona yii ki awon olupese itoju omode le mura ifisile won siwaju.

| Deeti | Eto agbekale ohun pataki |
|---|---|
| Ojo keta, Osu Kinni, odun 2022 | Akoko ibewe owo-yooda sii, awon olupese le fi ibewe won sile lori ayelujara nipase foomu ifakale ori weebu. |

| | |
|---|---|
| Ojo Kerin, Osu Kinni, Odun 2022 | Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland bere awon saa atileyin ise onibara nigbati awon asiko owo-yooda sile. |
| Ojo Kewaa, Osu Kinni, Odun 2022 | Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland bere asaayan ibewe owo-yooda ati ifitonileti awon olupese fun eye tabi awon ibewe ti ko pe/ti ko ye. |
| Ojo Kejilelogun, Osu Kinni, Odun 2022 | Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland di akoko atileyin ise onibara to kehin mu. |
| Ojo Ketalelogun, Osu Kinni, Odun 2022 | Ferese ibewe owo-yooda pade ni ipari Ojo Aiku, Ojo ketalelogun, Osu Kini, Odun 2022 |
| Ojo Kerin, Osu Keji, Odun 2022 | Gbogbo awon ibewe je atunyewo fun pipe ati yiye ni yiyan. Eka Eto Eko ti Ipinle Maryland yoo so fun awon olubewe nipa ibewe ti ko pe ati/tabi awon ti asise wa ninu ibewe won ni ojo yii. |

## Ki ni yoo sele leyin ti mo ba fi ibewe mi sile?

Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo bere asaayan awon ibewe owo-yooda lori ipile yiyi. Ni kete ti o ba ti fi ibewe sile, Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo se atunyewo ibewe naa lati jerisi yiye ni yiyan pelu ibaramu olupese si iye eye won (iye eye ti a pinnu gege bi agbekale ti a sapejuwe ninu isun yii ati ninu ibewe owo-yooda).

Ti ibewe ba ti pari ati pe olupese na yege, Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo so fun olupese nipa eye ati iye eye naa. Ti ibewe naa ko ba pe tabi Eka Eto Eko Ipinle Maryland se akiiyesi pe olupese kan ko yege, Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo fi to olupese leti (ko pe ju ojo kerin, osu keji 2022) yoo fun olupese ni ose kan (ojo isowo meje) lati yanju eyikeyi oran mimo.

Ti a ba se atunyewo ipile yiyi ibewe owo-yooda, Eka Eto Eko Ipinle Maryland nireti pe yoo pari isaayan awon owo-yooda ni kutukutu ibere osu keji. Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo pari gbogbo awon isaayan eye ni Osu Keta ojo kerin, odun 2022. Eyi tumo si pe Eka Eto Eko Ipinle Maryland yoo ti fi gbogbo awon eye sile fun alakoso fun owo sisan ni ojo yii. **<u>Lehin</u> ti Eka Eto Eko Ipinle Maryland ti fi alaye owo sisan ranse si alakoso fun isaayan, awon olupese le nireti lati gba owo ni ipinle lanrin ojo isowo meta si merin fun isanwo ACH (isanwo taara) tabi laarin ogbon ojo fun sowedowo ti a firanse nipase meeli deede.** Jowo se akiyesi pe awon idaduro ofiisi ifiweranse le gba akoko die sii laarin isaayan sisanwo ati iwe sowedowo.

### ISELE KINNI

Olupese kan fi ibewe won sile ni Ojo ketalelogun, Osu Kini, Ojo ikehin ti ferese ibewe, sugbon ko pe – olupese lairotele so faili ti ko too nigbati o n gbiyanju lati gba eda oni-nomba ti iwe-ase won. Eka Eto Eko Ipinle Maryland se atunwo ibewe pelu iwe-ase ati idahun ni ojo kerin osu keji, n beere pe ki o pese alaye atunse laarin ojo isowo meje. Ni Osu Keji ojo kakanla, olupese yoo fi faili imudojuiwon ranse. Alaye afikun naa je atunyewo nipase Eka Eto Eko Ipinle Maryland ni Osu Keji ojo kejidinlogun. Eka Eto Eko Ipinle Maryland lehinna bere ilana isiro re, yoo sii pari ise isiro re ni osu Keta ojo keta. Eka Eto Eko Ipinle Maryland fi alaye owo sisan ranse si alakoso lati se ilana ni Osu Keta ojo kerin. Olupese yan lati gba owo wole. bi ifowopamo taara, eyi ti o ti ni ilosiwaju ,owo sii de sinu ile-ifowopamo olupese ni ayika **ojo isowo meta si merin lehin Ojo kerin, Osu Keta odun 2022.**

### ISELE KEJI

Olupese kan fi ibewe won sile ni Ojo kerin, Osu Kini - ibewe naa pari ati pe gbogbo awon iwe ase je deede. Eka Eto Eko Ipinle Maryland se atunyewo ibewe naa o si so fun olupese nipa eye ni Osu Kini ojo kedogun. Eka Eto Eko Ipinle Maryland lehinna bere awon ilana ise isiro inu ode pari ise isiro re ni ibere osu keji. Eka Eto Eko Ipinle Maryland nfi alaye owo sisan ranse si alakoso ti o si ko sowedowo si olupese ti o fi meeli ranse nipase USPS. Sowedowo naa de adiresi olupese **ni ose die lehinna** (da lori akoko ifijise USPS).

# Ki ni ilana sisanwo?

Awon owo ebun italore yoo jẹ pinpin ni sisan leekan nilana lessee. Awọn olupese le tọkasi bi wọn ṣe fẹ maa gba owo sisan (owo ifipamo taara si ile-ifowopamo tabi sowedowo nipase USPS) ni ipari pipin ebun italore naa.

<u>Owo Ifipamo Taara</u>

Ti o ba gba ẹbun italore lakoko iyika akọkọ, o tun wa ni adiẹsi kanna, o nṣiṣẹ labẹ iwe-aṣẹ kanna, ti o si gba ẹbun italore akoko nipase ifowopamo taara, eyi tunmo si pe Eka Eto Eko ti ipinle Maryland ti ni alaye ifowopamo taara rẹ tẹlẹ. Ti ko ba ri bee, ti o ba fe gba ebun italore re lona ifowopamo taara, o ni lati fowosi foomu ifowopamo taara [Direct Deposit form](), ki o lo apo ifiweranse tabi fakisi si ofiisi Oludari, eyi ti yoo se eto ijẹrisi-idanimọ. Jowo je ki o to ojo Merinla lati ojo ijerisi fun Ofiisi Oludari/Alamojuto Owo lati seto ibeere re.

<u>Ṣowedowo nipase USPS</u>

Ti o ba yan lati gba owo sisan re pelu sowedowo nipase USPS, a o fi sowedowe naa ranse pelu apo ifiweranse si adirẹsi ti o pese. Awọn ṣowedowo ti a firanṣẹ pelu USPS yoo de leyin awon owo ti a san pelu ifowopamo taara. Eka Eto Eko ti ipinle Maryland ko le pese ipaṣẹ ati alaye ifijiṣẹ fun awọn owo ti a firanṣẹ pelu USPS.

# Ki ni mo le na owo naa le?

| Isori | Apejuwe |
|---|---|
| Owo Osise | O pẹlu awọn owo-iṣẹ ati awọn anfani fun awọn oṣiṣẹ eto itọju ọmọde; afikun owo fun eyikeyi oṣiṣẹ ni ile-iṣẹ itọju ọmọde tabi awọn olupese itọju fun ẹbi ati awọn oṣiṣẹ wọn; eto ma-da-n-dofo-eni fun ilera, ehín, ati oju; owo-iranlowo iwe kika; owo isinmi aisan tabi ebi; owo ifẹhinti; eto idagbasoke tabi eko ti nlọ lọwọ owo, idawole tabi sisanwo eewu; ebun owo osise; likiribibo owo oko-wiwo osise; awọn ohun amulo lati ṣe atilẹyin fun oṣiṣẹ lati ni aaye si abere ajesara arun COVID-19, pẹlu owo aaye ifisesile fun ipinnu ipade abere ajesara, ati lati sakoso awon ipa ajesara, tabi owo oko lati lo fun awon ipade ajesara |
| Iyalo/Idogo, awọn ohun elo, itọju, ati ma-da-n-dofo-eni | Awọn owo oya tabi idiyele pipe, ti ogimo owo sisan; awọn ilọsiwaju ohun elo, ti o pẹlu, ṣugbọn ti ko pin si, kikọ tabi igbegasoke awọn aaye ibi-iṣere, atunṣe awọn ile-iwẹ, fifi ẹrọ irin, awọn idagere, tabi awọn ilẹkun adaṣi lati jẹ ki ohun elo naa ni iraye si, yio awọn odi ti ko ni ẹru lati ṣẹda aaye afikun fun ifunra eni laye; itoju ati awọn atunṣe kekere lati koju awọn ohun to romo arun COVID19, awọn ilọsiwaju ti o jẹ ki awọn eto itọju ọmọde je ajumose ati aaye si awọn ọmọde ti o ni ailera ati awọn ẹbi ti o ni ailera ni a gbaniyanju; dika si awọn ilana iwe-aṣẹ lati wa ni ibamu |
| Ohun elo aabo ti ara eni, mimo, ati awọn iṣe ilera ati ailewu miiran | Inawo pato ni idahun si pajawiri ilera gbogbo eniyan si arun COVID-19 ati pe o le pẹlu ohun elo, awọn ipese, awọn iṣẹ, ati ikẹkọ ti o ṣe atilẹyin lati wa ni ibamu pelu ipinlẹ ati ilera agbegbe ati awọn itọsọna ailewu, pẹlu awọn ti o ni ibatan si idena ati ṣakoso ti awọn arun akoran, idena iku ojiji omode ati lilo awọn iṣe oorun ailewu, ṣakoso oogun (ni ibamu pẹlu awọn iṣedede fun ifọwọsi obi), idena ati idahun si awọn pajawiri nitori ounjẹ ati awọn irira, ile ati aabo agbegbe, idena ti aarun ọmọ ti o gbọn ati ibalokanjẹ ori irira ati aiṣedeede ọmọde, igbero esi fun awọn pajawiri lati ajalu adayeba tabi ṣẹlẹ ti eniyan fa, gbigbe ati ipamọ awọn ohun elo ti o lewu ati sisọ ohun ti o gbana nu, awọn iṣọra ti o yẹ lati gbe awọn ọmọde, ajogba ogun omode fun gbogbo ise ati CPR, ati idanimọ ati ijabọ ainaani ati aibikita ọmọ |

| | |
|---|---|
| Awon eroja ati ohun elo | Rira tabi awọn imudojuiwọn si awon eroja ati ohun elo ati awọn ipese lati dahun si pajawiri ilera gbogbogbo COVID-19. Niwọn igba ti ohun elo ati awọn ipese wa ni idahun si pajawiri ilera gbogbogbo arun COVID-19, wọn le pẹlu eronja inu ile ati ita gbangba ati awọn ohun elo ti o dẹrọ awọn iṣe iṣowo ni ibamu pẹlu awọn ilana aabo ati iṣe ti o yẹ idagbasoke, ati awọn ohun iṣowo ti o nilo lati dahun si ipenija titun, bii awọn ohun-amulo ati iṣagbega owo. |
| Eru ati Ise | O pẹlu eyikeyi ohun elo tabi iṣẹ pataki fun iṣẹ ti eto itọju ọmọde; apẹẹrẹ awọn ẹru jẹ ounjẹ ati ohun elo ati awọn ohun elo lati so ere dẹrọ, ẹkọ, jijẹ, iledìí ati igbọnsẹ, tabi oorun ailewu; apẹẹrẹ awọn iṣẹ jẹ ikẹkọ adaṣe iṣowo ati awọn iṣẹ atilẹyin, awọn iṣẹ pinpin, awọn iṣẹ iṣakoso itọju ọmọde, awọn iṣẹ ounjẹ, ati oko wiwo; o pẹlu awọn owo ti o ni nkan ṣe pẹlu iwe-aṣẹ ati awọn inawo ti o ni nkan ṣe pẹlu ipade awọn amuye iwe-aṣẹ |
| Eto Ilera Opolo | Lati ṣe atilẹyin ilera ọpọlọ ti awọn ọmọde ati awọn oṣiṣẹ; bi apẹẹrẹ, ibajiroro lori ilera ọpọlọ ọmọde ati ibẹrẹ igba ewe, ipilẹ-ẹri, ilana ti o da lori idena ti o ṣajọpọ awọn alamọdaju ilera ọpọlọ pẹlu awọn eniyan ti o ṣiṣẹ pẹlu awọn ọmọde ọdọ ati awọn idile wọn lati mu ilọsiwaju awujọ, ẹdun, ati ilera ihuwasi ati idagbasoke. ni awọn eto ibi ti awọn ọmọde ti kọ ẹkọ ati dagba; alafia awọn alabojuto tun ṣe pataki lati ṣe imuduro eka itọju ọmọde nitori ilera ọpọlọ ati ilera ti oṣiṣẹ ni ipa lori eko kikọ, igbanisiṣẹ, ati idaduro bii ipele itọju ti a pese fun awọn ọmọde; Awọn ibajiroro ilera ọpọlọ fun oṣiṣẹ ati awọn iru atilẹyin ilera ọpọlọ miiran si oṣiṣẹ jẹ itewogba |

## Nje mo ni lati toju iwe-eri fun inawo?

Lilo awọn owo ebun italore le wa fun ayẹwo. Rii daju lati ni igbasilẹ iṣiro deede ati pipe. Ti won ko ba na awọn owo ebun italore lori awọn ohun itewogba, tabi ki won lo o nilokulo, o le ni lati san awọn owo yẹn pada.

# Ibeere?

Ti o ba ni awọn ibeere nipa siseto tabi ilana ṣaaju ṣiṣi ferese siseto, o le kan si ọfiṣẹ Eka Eto Eko ti ipinle Maryland lori:

**IMEELI:** childcaregrants.msde@maryland.gov

**FOOMU:** Wo foomu ibeere wa inquiry form

Ogbontarigi iṣẹ alabara yoo dahun si gbogbo awọn ibeere laarin awọn wakati Merinlelogun tabi ọjọ iṣowo ti nbọ. Jọwọ ṣe akiyesi: Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo wa ni titi ni Oṣu kejila, Ojo Kokanlelogbon, Ọdun 2021 ati Oṣu Kini, Ọjọ Ketadinlogun, Ọdun 2022.

.

Ni kete ti ferese siseto owo ebun italore ba ṣi, Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo pese nomba foonu ti a yasọtọ fun afikun atil eyin alabara, pẹlu aṣoju owo ti a yasọtọ.

# Ti mo ba nilo iranlowo lati kopa nko?

Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo se apero ayelujara ti awọn osise atileyin alabara jakejado ferese siseto fun awọn olupese ti o ni ibeere nipa siseto ati ilana naa. A o pese alaye nipa bi o ṣe le forukọsilẹ lati darapọ mọ apero lai pe ojo. Wo ero weebu Office of Child Care website fun ekunrere alaye. Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo gbalejo apero alatileyin mẹta, won yoo tun fi awọn igbasilẹ apero kọọkan sori oju opo wẹebu won:

Awon Iwe-eri ti a Nilo

Webina: Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo pese akopọ ti eto ẹbun italore, won yoo ko awọn olukopa bi wọn yoo wa ati bi won ṣe le pari awọn iwe aṣẹ ti won nilo lati pari ati bi won yoo se fi fọọmu siseto ebun italore naa sile. Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo dahun si awọn ibeere ni akoko to ba ku.

## FOOMU ISETO

Webina: Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo ba awọn olukopa wo ibeere kọọkan ti fọọmu eto ebun italore. Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo dahun si awọn ibeere ni akoko to ba ku.

## IBEERE ATI IDAHUN

Apero Lori Ayelujara: Awọn apero yii yoo jẹ akoko fun ibeere ati idahun ki Eka Eto Eko ti ipinle Maryland le pese atilẹyin ti o ṣe regi fun awọn olupese itọju fun ọmọde bi won se lanfani.

Kalenda isalẹ yii jẹ ti awon akoko fun apero atilẹyin iṣẹ alabara. Alaye nipa bi o ṣe le forukọsilẹ ati darapọ mọ apero yii ni a o pese laipe ojo. Wo oju opo wẹẹbu website fun ekunrere alaye

| Deeti | Akoko | Koko-oro |
|---|---|---|
| Ojo Isegun, Ojo Kerin, Osu kinni | Ago kan si Meji Osan | A nilo awon iwe eri |
| Ojo Bo, Ojo Kefa, Osu Kinni | Ago Mefa si Meje Irole | Foomu Siseto |
| Ojo Abameta, Ojo Kejo, Osu Kinni | Ago Mewaa si Mokanla Aaro | Ibeere ati Idahun |
| Ojo Isegun, Ojo Kokanla, Osu Kinni | Ago kan si Meji Osan | A nilo awon iwe eri |
| Ojo Bo, Ojo Ketala, Osu Kinni | Ago Mefa si Meje Irole | Foomu Siseto |
| Ojo Abameta, Ojo Keedogun, Osu Kinni | Ago Mewaa si Mokanla Aaro | Ibeere ati Idahun |

# Awon Ibeere to saba ma n jeyolori owo iranlowo

Eka Eto Eko ti ipinle Maryland yoo je ki oju opo wẹẹbu ku oju osuwon pẹlu awọn ibeere ti won saba maa n beere ti o da lori awọn esi olupese jakejado ferese siseto owo ebun italore. Jọwọ maa wo oju opo wẹẹbu website fun awọn ibeere ti won saba maa n beere

# Asomo:

## AWOSE ITOSONA LATIKOWE FUN IRANLOWO OWO

## FOOMU OWO IFIPAMO TAARA

## FOOMU W-9